Chief Secretary to the Govnt


# EKO AKETE.

"EMI YIO FI OHUN TI O NDUN MAKUNNU HAN AWON ALAGBARA, NGO SI JE ALAGBAWI AWON ODI."—W. T. STEAD.

VOL. VI. NO 2[illegible]0 SATURDAY, SEPTEMBER 1, 1928. 4d.

The Leading Weekly Vernacular Newspaper in Nigeria.



## *White's Radical Gonkiller.*

:o:

(NATIVE.)

[ *A complete cure for old and fresh Gonorrhoea.* ]

When Gonorrhea is not properly cured, it gives rise to other troubles and diseases such as Barreness, Piles, Kidney Diseases, Stricture, Rupture, Rheumatism, Sore-eyes, etc.

**N.B.**—This Medicine cures Gonorrhea completely in either man or woman, so that no secondary diseases can follow.

Made from pure **Native Herbs,** and sold only by VICTOR WHITE, ESQ., *Chemist.*

41, Offin Road, Lagos.

PRICE: **Ten Shillings (10/-)** per bottle.

*Packing and Postage 2/6d. extra, to all parts of Nigeria.*

---

EGBOGI ALAWOTAN ATỌSI.

:o:

[ *Fun Atọsi lailai ati titun.* ]

Ti a ko ba tete wo Atọsi san daradara, o ma ndi enia lọwọ lati ṣe abiamọ, o si ma nfa oriṣi arun mi wa, bi:—Jẹdi-jẹdi, Aran, Iju, Ẹda, Ipake, Ase, Lakuregbe, Arun Oju, ati arun mi.

*N.B.*—Egbogi yi nwo Atọsi san lawotan patapata, ko si nję ki o ri aye wu arun mi silę.


SLOAN'S
N & B
FAMILY
LINIMENT
Trade Mark Registered
KILLS PAIN
Medicine Dealers
RELIEVES
Rheumatism
Neuralgia
Sciatica
Sore Gums
Sore Muscles
Sprains
Strains
Swelling
Tender Feet
Toothache
LOOK FOR
THE PORTRAIT
OF
Dr Earl Sloan
TO STOP
YOUR ACHES & PAINS
SIMPLY USE
SLOAN'S LINIMENT
Sold by all Dealers.
Wholesale: Fassett & Johnson Ltd
Clerkenwell Rd. London Eng.

*Editor & Proprietor:—*
ADEOYE DENIGA,
*Office* 24, Williams Street,
Lagos, Nigeria.

ASAN-SILẸ NI OWO GBIGBA RẸ.

| | Eko. | Ilu miran ni Nigeria. | Ilu Okere. |
|---|---|---|---|
| Ọdun kan | 12/- | 13/- | 14/- |
| Oṣu mẹfa | 6/- | 6/6d. | 7/- |
| Oṣu mẹta | 3/- | 3/6d. | 4/- |

Ẹ fi owo ati *Letter* ranṣẹ si *Editor*

## GBOHUN-GBOHUN.

PAGIDARI ! ! !

Jẹnnẹjẹnnẹ mu ẹnikẹni ni *Monday* (sẹ yi nigbati Ilu gbọ irufẹ Idajọ ti Adajọ Ọgbẹni H. A. Young da Ọgbẹni Herbert Macaulay ati Dokita Kọkriki nipasẹ ọrọ agbọsọ ti tẹmbelẹkun ibọn yiyin fun Prince Eṣugbayi Eleko.

IKU DẸDẸGBO.

Awa Mọto kan fi Mọto rẹ kọlu opo Waya Ẹlẹktriki kan ni gbalasa Ita Tinubu ni alẹ Satide tokọja, ọgafa bẹni oyinbo Olori awọn ọlọpa inu ati ọlọpa ode kan ti duro si ibẹ ti nwọn si nle awọn enia sẹhin lati maṣe sunmọ ibi ewu yi, eyiti a nwi tipẹ bẹni awọn Olori ọlọpa ti tẹ Waya si Ile ina na, afara kosi nwọn si pa awọn atupa ti o mbẹ ni ogbonrọngbọnrọn ibẹ: o to igba diẹ ki nwọn to le pari iṣẹ siso waya to ja na pọ, lẹhinna ni ina apa ibẹ ṣe tan. Ka jẹ pe awọn Olori ọlọpa ko fiyesara ni, jamba ti Waya ajinipa bi ẹja ojiji yi le ṣe ki ba ti ṣe fẹnusọ.

## DURO SOTỌ.

[LABARI LATI ỌWỌ GBAJUMỌ.]

EYI ARA!

Ni arin ọsẹ to kọja ni oru ọganjọ ni dede agogo mọkanla nlọ lu, li a ngbọ lapa adugbo kan, bi ọkunrin kan ti nlọgun oni-burẹdi ti o nke kakiri adugbo na, eyi mu ki awọn aladugbo na fi nṣe yẹyẹ wipe tabi ko jẹ burẹdi ri ni, bẹni awọn ẹlomiran si kanu rẹ wipe tabi ebi lo fẹ si i ninu fẹrẹ—lai si tabi-tabi, eniti o ba ngbọ bi ọkunrin na ti nke 'bosi oni-burẹdi nitotọ lọjọ na, yio sọ wipe ko daju bo jẹ burẹdi ri lati ọjọ ti o ti de aiye—papa gidi bawo ni oni-burẹdi ti ṣe wọn bẹ fun okunrin na lọjọ na?

TANI NI ỌMỌ NA?

Geregan ni ọmọ kekere kan yọ si oju ọna mọto ni *Victoria Road*, ni eti Ita Tinubu ni irọlẹ ọjọ Satide to kọja—bẹni mọto kan nkun bọ bi arira, nibẹ ni gbobgo awọn enia nke ha, ha, ha, tani ni ọmọ na! ọpẹlọpẹ ọmọ kunrin kan to fo tan-un si odi keji bi ẹkun ti o si he ọmọ na lapa kanun bi ọrọ iba ti dun mọ ni iyẹn ki Ọlọrun ṣọ ni nibẹ, bi ko ba si awọn Dẹrẹba omiran bi awọn eyiti nwọn npe ọmọ-ọjẹka, a ni lati ma ṣọra ọrọ sisọ nigbati a ba ngbo wipe moto ṣe omiran leṣe loju ọna rẹ nitori aibikita awọn ẹlomiran fun awọn ọmọ wọn, ṣugbọn ẹru kan lo nmu ni bu igba ẹru, nitorina ẹnyin ọlọmọ wẹwẹ, ẹ bojuto awọn ọmọ nyin barafo nitori idagri ọna.

FINLE-FINLE

A tun ko firi awọn ti awọn Alabojuto ilu yan fun finfin tabi fun pipa awọn ekute ni apa Agbomalu ni ko i pẹ yi, ṣugbọn a ko mọ bi awọn ti iṣaju tabi awọn omiran titun ni, boya ọfọ kan lo si ṣe, lojọ wo ni a ma mu ekute ilu yi tan ti a o fi bọ kuro lọwọ ajakalẹ-arun, tabi arun ekute ilu, Oluwa rere jọwọ gba, a i ke a nyan fun Ọ.

KẸLẸ KẸLẸ KẸLẸ RẸ DẸRẸBA.

Ẹrin ni on ẹrin ni irọlẹ ọjọ Satide ijẹjọ nigbati ọmọdekunrin kan ni on nto mọto alugbagba kan bọ lati ọna Palm Church Street, ti o si ni ki on ya si adugbo Oluwọle bẹni mọto dori kọ ile onile kan, lo ma fẹ fi fa mọto na pada, nigbati ọwọ Dẹrẹba na ngbon riri bi ẹiyẹle Subuana—ko daju bi oyi mọto ti da loju Dẹrẹba na.

IKORITA-MẸTA.

Iba dara julọ bi a ba le ri ọpa Ọba kan ni agbede-meji Williams ati Broad Streets fun itọju awọn mọto, nitori ibẹ nfo enia laiya ti mọto ba nbọ lọtun-losi, a bẹ'ri o ẹnyin ọga Ọlọpa.

AGARAWU STREET.

Bẹni iba dara julọ bi awọn Alabojuto ilu *Town Council* ba le jẹki nwọn kun Titi Ita Agarawu ni ohun ti o ti bẹrẹ lojude isọ ẹran ni ọja Ereko titi lọ de gẹrẹgẹrẹ ibiti opin Irin Reluwe agbe-gbẹ

wa, gęgębi o ti ję wipe, ibę ko wulo to fun kękę ologere lati rin.

## DAVIES STREET.

Bęni a si tun şe akiyesi ebutu kan ti o wa ni Davies Street, ni ojude Şukuru Onidunkun, (eyiti ko fun kękę-ologere ni agbara lati sure to bi o ti fę,) fun awọn *Town Council* lati din iyępę na ku tabi lati şe atunşe ti o yę sibę.

## ANSARUD-DEEN KEKERE.

Awọn Jamat Ansarud-Deen kekere şe aisun kan ni Ita Balogun ni alę ojo ọsę ijeje fun ayọ ọjọ ibi Anabi wọn Mọmọdu *Sila-alahu alaihi wasalam*, ọjọ-ibi yi ni nwọn npe ni "Maolud" ni ede awọn Larubawa tabi "Birthday" ni ede Gęsi: ọpọlọpọ enia ni okunrin, ni obinrin, ọmọde ati agba lo wa sibę ati awọn ero iworan ti nwọn wa fi onję oju fun oju—A şe 'yi şe 'mi o!

## JAMAT AHMADIYA.

Bęni awọn Ijọ Ahamadiya papa şe aisun ọjọ-ibi Anabi Mọmọdu yi papa *Peace Allah be on Him*, ni Mọşalaşi Jimọ ti o mbę ni Arọlọya Street, ni alę ọjọ *Sunday* to kọja na; ọpọlọpọ rę o!—amin.

## ỌJỌ IBI ANABI MỌMỌDU.

Gęgę bi ọjọ *Monday* ijęfa ti nşe ọjọ Anabi Mọmọdu fun awọn Musulumi jake-jado eyi ję ọjọ pataki fun wọn.

## ALAJI BAKO N' MỌKA.

Awọn Jamat kan ti o ję Alaji lọ şe ariya kan ni okun *Victoria Beach* ni ọjọ Atini ijęfa nipa ọjọ-ibi Anabi Mọmọdu kanna, a gbọ wipe nwọn ko onję dani lọ rępętę bi eyi ti o nlọ si idalę.

## JAMAT MUSULUMI.

A ki Lemomu Ikiali ati awọn isangbe rę nwọn ku ọdun yi ki Ọlọrun fi ọpọlọpọ rę wọn o, si atari anfani.

## OJO ARỌKURO.

Ojo winrin-wiurin bęrę si rọ lati ọsę keji eyiti o tun bọ nfun atęgun owurę ni agbara, şugbọn lęhin ojo yi a o bọ si inu aseko-ęrun fun igba dię ki a to bọ si inu şanmani ọyę eyiti o mbọ si inu oşu Keresimesi, ki Oluwa gbe wa leke atęgun tabi ajalọ ọgęnętę yi o,—amin.

## ADURA NI ĘBỌ IMALE.

A gbọ wipe awọn Musulumi şe adura nla kan ninu Mọşalaşi Jimọ nla wọn ni ọjọ ọsę keji ohun fun oye ewu ti a ro wipe nwọn ri larin ọdun ni —Ọlọrun ko gba adura o bi o ti gba fun onişę-nla, ki ilu roju ki a ri owo ki a ri ọmọ olubori rę ni alafia—Fatia janma.

## IKU DI MEJI OKAN.

Iku ti a ngbọ wipe o nọa wọn lode oni ko şe sọ, o ti kọja ękun o di ọran ęrin, ninu gbogbo rę julọ ewo ni Asarayilu ti Ọlọrun ewo ni ti Anjọnu ati si awọn ọmọ Anabi Adamọ? Ju gbogbo rę lọ ohun gbogbo ko şęhin Ọlọrun, ki Oluwa gbe wa leke musiba ọsan, musiba cru, musiba alę, ati ti arọ ninu igba ti a wa yi o.

## GBAGA! NKAN MBĘ.

wo awọn koni, wo awọn akin, wo awọn alagbara bi nwọn ti nşubu loju ogun wọn, ti wọn si nduro gan-gan-gan sori alamọri wọn—Nigbati awọn enia buburu ba gbęręgęjigę ti nwọn nsọ wipe ko si iru wọn mọ bawc ni ęmi ki yio ti şai gun to lori iwa won; şugbọn adunbudęrę ęsan mbọ fun olukuluku ọmọ Anabi Adamó gęgębi ere işę rę.

## OMI-IJU ATI AGEGE.

Anu şe wa dię lati sọ wipe nigbati a de Agege ni ko i pę yi a ko ri anfani omi-iju ni arin ilu yi gęgę bi a ti ni ero, to bę ti o fi ję wipe nwọn fi owo ra omi mu, fun ęniti ko ba ni akikanju lati lọ pọn omi ninu odo ti nwọn gbe npọn omi na eyiti awa ko bikita fun lati ri titi a fi kuro nibę, nitori ki işe omi bi iru ti Iju ti awọn Munisiba fa wọ arin Ebute Męta ati ni arin Eko, ti o si ję ohun iwulo fun wọn gidigidi loni.

Lori eyi wayi o, o wa tun ję ohun iyalęnu fun wa lati sọ wipe awọn ara Agege ko ri omi iju lo, ni iwọn igbati o ję wipe ni eti ọdọ wọn, ni awon Munisiba ti fa omi yi wọ Eko ati Ebute Męta, ki li o wa fa sababi yi kę? nitori awọn lo yę ki nwọn kọkọ ri anfani omi na ję, gęgę bi o ti wa ni itosi ọdọ wọn ju ihin lọ, ati pęlu o yę ki nwọn ni anfani omi na daradara nibę nitori ęniti o ba de Agege yio ri wipe o ti kuro ni ibi ti a le pe ni ileto tabi ọja kan lasan.

Şugbọn ewo ni awọn ara Agege nşe si? Nitori ai ni omi na fęrę bu wọn ku loju wọn, o şi yę ki nwọn şe şawura pataki kan si bę fun anfani awọn ara Eko ti nwọn nlo sibę, i omi-iju si ti mọ lara fun mimu.

## ATI JĘUN IJANGBAN.

Anu şe wa lati ma gbọ ni ęnu ọpọlọpọ awọn ęniti o nta ọja tabi ti nwọn nşowo *trading* ti wipe gbogbo wahala owo *trade* ti olukuluku wọn nşe ko lere lori ęlomiran nipa a nwa ọna lati jęun o tun fi da gbese ni—ijangban a ti jęun lo ma ni on nşe o, ipaiya ti igbere yio tun wọ ọ, awọn ęniti nwọn nşişę loju mejeji ti nwọn si ngba owo geregere ni ibi işę nkọ, a ha tun le şęşę sọ ti awọn ęniti ko ri işę şe tabi awọn ęniti nwọn nro bi nwọn ma tişe le san gbese oni-gbese ti nwọn gbe sọrun ti nwọn si mbę lori kila-kilo fun eyi, ewo ni ko ję ijangban o ęnikeji lori gbogbo ere a ti jęun ni.

larin gbogbo wa mọ Amin. Iṣu ati ọbẹ o wa ni ọwọ awọn Ọlla ati Okunlaru. Owe awọn kan ni Alagba wipe Awo ile ko ni ewọ o difa fun onigba Ẹni ore, nwọn ni ki o fi ikan ṣoṣo ru ẹbọ, o kọ o ni ki ṣe ori on rara ki gbogbo rẹ wa jona patapata owe ni o. Ki Ọlọrun ma jẹ ka ri buburu.

Ohun buburu ni nyọ ofa ninu Apo, ohun rere ni nyọ Obi ninu Apo, iyẹn ni o da Ita fun obi aiya ati okọ aiya o. owe ti ẹnyin Alagba o. Ki Olọrun Oluwa Olodumare ṣanu fun Ọba Alapẹru ati awọn Ijoye rẹ ati gbogbo idile Ọba Alapẹru, ki Ọlọrun ṣanu fun gbogbo wa o, Amin. Awọn ara Ikorodu kọ orin kan ni ọdun oro wọn.

Emi ni tiyin,

J. A. O. SHOMADE.

---

## AṢOTITỌ KI SUN NIPO IKA

Nigba lailai ni a ti ngbọ ti awọn Baba nla wa ma npa lowe bayi pe aṣotitọ ki sun nipo ika, o si jẹ ohun ti asiko igba lailai ti ọrọ kan ba ja kun diju, nwọn a wipe ko si nkan otitọ ni yio leke bẹni otitọ ni yio leke bi ọjọ ku bi oju agogo, o jẹ ohun abami loju opọlọpọ enia lati mọ ohun pataki ti o ṣẹlẹ ni ọjọ *Monday* ọsẹ yi, ṣugbọn pataki kini epo ṣe to fi di ọta adi. A ko fi ba ẹnikẹni wi arara ẹla lọrọ, ṣugbọn bi a ba nri iyipada tabi idanwo eyi ti o jẹ pe o wa fun ẹnikẹni. ẹ jẹki a ma ranti pe ọrọ kan sọ bayi pe: (*Rejoice not against me my enemy, when I fall I shall arise; when I sat in the darkness the Lord shalt be a light unto my path*) eyi ti a le tumọ bayi pe ma yọ mi iwọ ọta mi nigbati tabi bi mo ba ṣubu emi yio dide; bi mo ba joko ni okunkun Oluwa ni yio ṣe imọlẹ mi, ẹ jẹki nma ba ọrọ mi bọ gẹgẹbi mo ti nba bọ. Aṣotitọ ki sun nipo ika, aṣotitọ a ma sun nipo, ika ni ko ni sun nipo aṣotitọ lailai, awon ọkunrin olokiki meji kan wa nigba lailai orukọ ekini a ma jẹ Aṣotitọ orukọ ikeji a ma jẹ Ika awọn mejeji wa ni ilu oke rere si ara wọn gẹgẹbi Kaduna si Eko yi olukuluku nba iṣẹ tirẹ lọ, eyi to jẹ pe yio fi jihin fun Olodumare gẹgẹ bi olukuluku awa na ti ndi ẹru eyi ti a o fi jihin fun Olodumare ti ti won, ti ẹlomiran ninu wa nṣika imiran ọdalẹ ekute jẹni fẹni eyiti ẹlomiran ninu wa nṣe aitọ nipa ṣiṣata ti ko tun ilu rẹ ṣe, iwa ma jẹ, ma lọ, ṣugbọn agba ti o gbin ebu ika ori ọmọ rẹ lo gbin le, ni ọjọ ti o ba si bẹrẹ si hu ọmọ rẹ ni yio wu jẹ mo ni olukuluku nba iṣẹ tirẹ lọ nigbati o di ọjọ kan ẹnikini dide lati lọ si irin ajo ẹnikeji dide lalaiko mọ ilu ara wọn, nwọn pade ni idalẹ larin ilu kan ti o gborin ṣugbọn iṣẹ olukuluku ntọ lẹhin, nigbati o ṣe awon mejeji jọ pade ara wọn, nwọn si di ọrẹ laipẹ ọrẹ wọn na ko pẹ lọ titi ki ija to de larin awọn mejeji, Ọba ilu na si jẹ ọlọgbọn o pe ekini ati ekeji pe ki on ba pari ija fun wọn, Aṣotitọ ko ẹjọ tirẹ o wi, Ika ko ẹjọ tirẹ o wi, Ọba la ija na fun wọn o da Ika lare, nitoriti Ika wa lapa ti Ọba. Aṣotitọ wa sọ bayi pe on ti mọ pe ọrọ yi ki ṣe ọrọ eyiti on le jare rẹ, Ọba bere—Aṣotitọ sọ pe ohun ti o mu on ki on to wi bẹ ni pe otitọ koro pupọ gẹgẹ bi ewuro eyiti enia ko le fun omi rẹ mu ni tutu bẹni otitọ ri, ṣugbọn bo da are Olodumare yio tun da, bo tun da are Olodumare yio tun da bakanna.

Ọba ni o dara on o ma wo awọn mejeji Ọgbẹni Ika yi bẹrẹ si ma Bisi, gbogbo nkan rẹ si nlọ daradara okiki rẹ nkan to bẹ ti won fẹrẹ mọ ka gbogbo aiye ni sa igbana, ṣugbọn Ọba mi Adakẹdajọ si nwo awọn Ọgbẹni mejeji wonyi nigbati o ṣe nkọ aisan kọ lu awọn mejeji o si wa jẹ pe nigbati Ika wa ninu aisan, ogun kan bẹrẹ ni akoko na eyiti o jẹ pe ogun na lo pa gbogbo ọmọ ati obinrin ti o ni, ki Olodumare ba le ṣiṣẹ, o wa ku Ika ni kan ṣoṣo, laipẹ Ika ku nitori ko si onitọju fun mọ, Aṣotitọ si ku pẹlu nwọn ti gbẹlẹ ibi ti nwọn ma sin Ika si tan, nwọn si tẹ oku rẹ pẹlu ohun meremere ti nwọn fi ṣe lọṣọ, nwọn gbe ina atupa ka apakan koto, wọn wa aburo tabi alabagbe Ika ti yio bu erupẹ si loju ki nwọn to sin, nigbati nwọn o fi pada de ina atupa ti danu si nu koto oku Ika kaiyi gongọ ina nyọ ku iyoku diregbe Ika ti jona tan panapana ki nwọn to pada de, koto ti di ofifo, ki ni won ti ma ṣe bayi oku otitọ lo wa nilẹ ti awọn koi ti sin yi bẹni iho Ika ti di olo, ni wọn ba gbe oku Aṣotiito nwọn sin sinu Ipo Ika, nitori pe Ika ti jona, nitorina ẹniti o ba nṣe rere ki ma ṣe niṣo, ẹniti o ba nṣe ika rẹ ko mo ṣe niṣo, ere mi mbẹ pẹlu mi lati fi fun olukuluku enia gẹgẹ bi iṣẹ rẹ tiri, ẹ ko ri igbẹhin Ika ati Aṣotitọ ṣugbọn ẹ gba gẹgẹ bi orin awọn Imale ti nwọn ma nkọ bayi pe pẹtẹpẹtẹ ti ẹn na ni papa o, to nile talejo ni yio ta si, to nile talejo ni yio ta si, ẹnyin olọtẹ o ṣe si apa ni bayi o fẹrẹ tun ṣẹ si itan na. Ko si ẹniti ko ni kan dajudaju pẹtẹpẹtẹ ti ẹ nta si ara nyin 'lara ko ma si ẹnikan ti ko ni kan o.

Emi ni ti nyin nitotọ,

ENIA ṢORO.

---

# IROHIN ONDO.

---

## EYI ARA, ẸRỌ TITUN DODE.

A ṣi Ile-Ẹrọ Itẹwe titun kan si opopo Igunrin Street, Ode Ondo, ẹro yi ntẹ boto ninu, iwe ketekete ni iwe rẹ han, a ba awọn ara ilu Ondo yọ fun irufẹ iṣẹ ribiribi ti o bẹrẹ larin ilu Ondo papa lakoko ti Ọba ṣẹṣẹ Dade ni inkan titun ba yi ṣẹlẹ lakoko tirẹ, a si ni reti pe awọn ara ilu yio mu iṣiri ba awọn ti o mu iru iṣẹ ba yi wa si arin ilu Ondo nipa fi fun wọn ni iṣẹ ṣe, bi ẹrọ itẹwe yi ti ntẹwe alarabara to bẹni Ọgbẹni wa Mr. S. Ọla:

Awoşika ẹniti o jẹ alakoso işẹ yi, bi o ti wu ki iwe jato bi o ba ti de ọwọ rẹ a di titun. Adura wa ni ni pe ki Ọlọrun Olodumare ki o fi idi işẹ na mulẹ eyini ni pe ki o şe iri ibunkun Rẹ si ori işẹ na.

## ẸGBẸ SERAFU ŞE OHUN ARA.

Kabiyesilẹ fun ọba aiku ni ohun totọ lati fi yin Baba nigbati ari awọn Ẹgbẹ Serafu ni irọlẹ ọjọ kẹrindilogun oşu August yi 1928. Ni agogo marun abọ awọn ẹgbẹ yi sọjade kẹwu ni Ode Ondo lati fi iyin fun Ọlọrun Olodumare nigbati mo boju wo opopo Igunrin St. Ha a şe mi gẹgẹbi ati ri ninu iwe Mathew ori 15, ẹsẹ 31. O dabi ẹnipe awọn Angẹli Ọlọrun lo sọkalẹ wa si aiye. Nigbati awo Iya Ẹgbẹ Serafu ti Ode Ondo larin wọn o dabi iranşẹ birin Jesu ti Ọlọrun papa ti yan fun ararẹ gbogbo awọn ọmọ Ẹgbẹ Serafu si funfun lau gẹgẹbi Snow, nigbana ni ọkan mi si sọsi ikan ninu orin Dafidi ni Plsam ori 92, ẹsẹ 1–2, ati 6. Mo fi orukọ Ọlọrun bẹyin ẹyin ọmọ Ondo ki ẹ tubọ tẹrama igbagbọ nitoripe Ọlọrun papa ko fi ohun-ohun du nyin. Nitorina ki ẹ ranti owe ti awọn Ondo npa pe igbati ẹhin ba wa lẹnu ni a njijadun Ekuro ki ẹ lọ ba mi wo iwe Oniwasu ori 12, ẹsẹ 1 titi de 6, ati iwe Oniwasu ori 9, ẹsẹ 10.

## INA O! INA O!

Nigbati o di alẹ tan ni agogo mẹjọ ku ogun işẹju okiki ariwo nla kan so gẹ ni a ka ẹrinkẹta arimari ni a gbọ pe ile Chief Rokunkan ni Ina njo ni apa ọtun ni abalọsi Mission yard ogbokowo Ode ondo, ọpẹ fun Oluwa pe Ọlọrun jẹki ọpọ enia wa nile. Rev. S. C. Phillips ko mọ bi on tişe gun Motor Cycle debẹ lai tan atupa si inurẹ a kole sọ işẹ ti awọn Olọpa Eko şe nibẹ ni alẹ yi awọn Nigerian Police, mo si fi iyọnu Ọlọrun bẹyin ki Ha a maşe şe yin pe awọn Serafu jo yilu po loni pe ina si jo lalẹ ki ọkan yin maşe gbọgbẹ fun eyi nitoripe ari ka ninu iwe Owe ori 13, ẹsẹ 12, ati 13 pe ireti pipẹ mu ọkan şaisan.

## IKU PI BI ẸNI PA INA, ORIŞA P'AWO P'ỌGBẸRI.

Ọşe! Madam Ọtẹkunmi Iya Ladiran lọ si ibugbe isimi, o dun ọpọlọpọ enia pe Iya oninure yi ko şaisan tẹlẹ nitoripe ni alẹ ana nigbati ina njo ile Rokunkan Madam Ọtẹkunmi jade si ita oşe ajo gẹgẹbi gbogbo enia ti nşe nigbana afi bi asi ti gbọ iku rẹ larọ yi ni agogo mẹfa abọ.

Iya ọrun re o.

## IKU ORO RẸ DA, IBA OKU IŞẸGUN RẸ DA.

Anu şe ni lọpọlọpọ nigbati a gbọ iku Madam Laşiku ẹniti o fi aiye silẹ ninu oşu ti o kọja ile rẹ wa ni okesare, iya yi jẹ oninure ninu awọn obinrin o si jẹ olufọkan sin enia adura mi ni pe ki Oluwa ki o gbe si afẹfẹ rere.

## A! IRU IDAN WO LEYI.

THE GREAT ABUDU (MAGICIAN).

Ẹru ba ni lọpọlọpọ nigbati Ọgbẹni ti a darukọ rẹ loke yi wa pidan fun wa nihin ni ọjọ kẹsan ati ọjọ kẹwa oşu yi, ni ile ti a ndajo o şe kisa ninu ere o fi fila sebẹ o fi ẹnu ye ẹhin bi adiẹ, o paşẹ fun inuju (Handkerchief) ki o ma jo bi enia, a ko le ma darukọ awọn oniruru ere ti o şe ni ipari ere rẹ o paşẹ pe ki ẹnikan yinbọn si on won si yinbọn si lẹhin işẹju marun o dide o si pọ gbogbo ahaya ti a fiki ibọn na lẹnu ara rẹ.

Emi ni tirẹ nitotọ,

ẸKIMOGUN.

---

## INA WỌLE OKUNKUN PARADA.



Atupa ti a npe ni "Oşupa mi" jẹ ojulowo ati papin atupa hanun ti o si yẹ ilekile, papa ile awọn gbajumọ olowo, a ko le şẹşẹ ma sọ ti awọn "Dẹngọ". Agbara rẹ pẹlu agbara atanpọ ọdunrun abẹla, dede ni, bi ọsan si ni titan rẹ ri ninu ile. Agba ti koi ti lowo gbigba Atupa Şango sile ki o ma jafara lati ra atupa meremere yi ti o na electric jẹ.

Orişi meji lo wa fun tita: ti oni-fadaka ati ti onidẹ

Ẹ lọ yan ti nyin ni Şabu Oyinbo KESSLER ni No 7, Labinjọ Lane.

Ẹnyin ara-oke ati ilu miran, ẹ maşe gbẹhin ki ẹ to ranşẹ ri nyin, ki ẹ ma ba j'oku ologbo.

**EKO AKETE**

EKO, SATURDAY, SEPTEMBER 1, 1928.

## HERBERT MACAULAY.

Girigiri ęsę ati ọpọlọpọ ękun ati ohun aro ti o gba Ita Tinubu kan ni *Monday* ọsę yi nipa idajọ ti Adajọ Kotu awọn Ọlọpa ni Santana da Ọgbęni Herbert Macaulay pe on fi si ęwọn oşu męfa nitori jijębi alamọri ọrọ agbọsọ ti ọtę ibọn yiyin fun Prince Eşugbayi Eleko nigbati o ba mbọ wa si ilę yi, ka gbogbo Eko lara bi aşa imu: kete ti Adajọ na ti şe idajọ rę tan ninu eyiti o ni ki Dokita Caulcrick san Adọta pọun tabi bibękọ ki o lọ si ęwọn oşu męta, bęni ọja Ararọmi, Ita Faji ati Ereko tu pę ti aimọye enia lọkọnrin lobinrin dorikọ Ita Tinubu boya nwọn jẹ le foju gauni ęni wa yi ki awọn alagbara aiye to mu lọ; fun odidi wakati męta lęhin idajọ na bayi ni ero nwọ lọ ti nwọn si nwọ bọ ti ękun npe ękun ranşę; titi ilę *Monday* ọsę yi fi şu ni gbogbo ilu pa lọlọ bi ęnipe ọfọ nlanla lo ku şę. Idajọ ti a da Ọgbęni Macaulay yi ya wa lęnu nitoripe riro ęjọ na ko şe ęhin wa ni Kotu Santana yi, loju wa ęri ti awọn isọri isọri enia na jẹ fun Ọgbęni wa na to lati fi da lare nigbati a ba si tun ro ti ọrọ pataki ti Ọlọla Moore so pe ki şe ęşę ti ęniti o gbọ agbọsọ ba le fihan pe ohun bayibayi ni o jẹ ki on gbagbọ, idajọ ti Adajọ da Ọgbęni Macaulay şe ni loju su. A gbọ pe ohun-aro kekere kọ ni o gba gbogbo ilu oke kan nigbati nwọn gbọ ti ajalu nlanla yi, tobę ti o fi jępe ọgọrọ awọn enia lo fęrę diji pe irohin na ba le jẹ otitọ bi.

Lati igbati işęlę yi ti şęlę ni omine ti nkọ purọ enia pe nję irufę ikọsę nla yi ko ha ni jẹ idalọwọkọ fun ọrọ ęjọ Eleko bi; a fę sọ-fun irufę awọn enia bayi pe, ohun ti o şęlę na iko le di ęjọ na lọwọ niwọn igbati awọn lọya meji korogba korogba Ọgbęni Ọlọla Eric O. Moore ati Ọgbęni J. Kushika Roberts ti wa lęnu ọrọ na.

Niwọn igbati Ọba King ti pa laşę pe ki nwọn gbọ ęjọ Kotu ganran na ni ti *Nigeria* kosi ęniti o le mọ l'ęwa ki o yan run nipa riro aşę yi ti sapakan odidi Ọba King lo fọwọ si iwe aşę yi pęlu awọn Igbimọ rę, kişe oyinbo abọrikura kan ti ęnikan le yi ni agbo danu nitorina a fę ki ęnyin Ilu lo fi ọkan balę nipasę ọrọ Eleko na işe Kotu ni; lọya meji si mbę nidi ọrọ na nisisiyi iruire ọpọlọpọ ko şai si fun awọn ti nwọn ti nru ęru gbogbo ilu ibaşę niti ọrọ ti o kan gbogbo ilu tabi ọrọ Isin, ęnyin ọmọ lęhin Onişęnla ko şai ka ninu iwe itan irufę iya ti Anọbi Mọmọdu farada ki o to le fi Isin Imale mulę, ę ko ha şe iranti ọgọrọ ọtę ti awọn ara ilu rę disi nigbati o njişę Olodumare fun wọn pe ki nwọn lọ ko orişa ti wọn nsin danu ki nwọn si bęrę si irun kiki, nję sisọ kọ ni nwọn sọ ni okuta ki o to sa lati *Mecca* ibi ti a gbebi ti o si lọ si *Medina* bakanna si ni inira ti o wa fun Anọbi Isa ki o to fi isin igbagbọ mulę fun awọn onigbagbọ bi o ti wa ni igba lailai bę lo si wa ni aiye ode oni, nigbati ibi meji ba şigun si ara wọn ọgagun ni awọn ọmọ ogun yio ma fi ọta sun lati mu ki ogun ba şępa. Talo le sọ pe Ọgagun nla kọ ni Ọgbęni Macaulay ęniti o ri inira ti Ọgagun k'ọgagun ma nsaba ati ri. Ọta le ma yọ, nwọn le ma yọ şuti si, nwọn le ma kọ ikọkukọ sinu iwe-irohin bę ha kọ ni ọta yọ şuti si Anọbi Isa tabi Anọbi Mọmọdu nijọ kinni?

Lakotan ę jẹ ki a fi yedenu ki a si tọrọ adura ki ęniti o ja mọ ilu loju lojiji yi le tun pada bọ wa sipo rę lęhin opin akoko oşu męfa ti Adajọ bu fun.

Tanimęhin?

## IROHIN ILE-IFĘ.

A gbọ wipe Ọgbęni E. T. Adewọyin Coker ti o da kan lọ si ajo gęgę bi ati so ni ọsę to koja, yio duro dię ni Ikire, Ibadan Abęokuta lęhin na yio pada wa sile titi oşu kan loni. Pęlu ilera ni o fi lọ ni ọtę yi osi lọ pęlu Iyawo rę Oburo Felicia

Idowu ati awọn ọmọ rẹ Abiọdun ati Taiwo—ki Oluwa ki o pa alọ ati abọ rẹ mọ si arin wa. Aṣẹ o.

Lẹhin ti Ọgbẹni A. R. Mọsanya de Eko o si ni ki aba on dupẹ gidigidi lọwọ Ọba Ọni Alayeluwa fun ọrẹ to ta on, ati awọn aya Adewọyin Coker, Bayẹmi, Idowu, Ọlọra, Aṣimọwu fun ọrẹ rẹ si on ati ajo wọn nipa jijẹ, mimu ati ọgbẹni Arogundade awo Ekurọ fun alejo ti o ṣe ohun nigbati on wa ni arin wa. Ohun to jẹ ka jihin rẹ bayi nipe bi ọmọ ba tiri ni a nṣe anọ rẹ, Ọgbẹni yi ko le ran hin tan oriṣiriṣi ase ti wọn se fun on, eyi yatọ si ase ti Punkard Boy, alejo to yanju gedegbe ni eyi. Cẹgẹ bi ati mọ Ajasa si lọtun losi ibatan Ọba ni Eko ni o jẹ nitorina ẹni iyi ni, osi tun ni ki aniran ki Oloye Jagunọshin fun on oku ina wo ọjọ.

O dun mọ wa ninu wipe ọrọ ara Ọyọ pẹlu ara Mọdakẹkẹ nṣẹ ngberan, nitori na afi Odua bẹ Ifẹ ki wọn ma jẹ ki iya jẹ ara Mọdakẹkẹ gbe nitori ko mọ iwe. Ọyọ Mọdakẹkẹ sa yatọ si Ọyẹ Ogbomọshọ. Bi Ifẹ ka loni yi Ọyọ Mọdakẹkẹ la ma ri, ki ara Ọyọ yi dabọ o, ko gba owo rẹ pada ki onile fi ọwọ mu le. Bo ba ma kọ ko tọrọ ilẹ ni ọwọ Ọba Ọni Kabiyesi Alaṣẹ Oriṣa.

---

## ỌJỌ—IBI.

---

LATI ỌWỌ KEKERE-AWO.

Si Oniwe Irohin *Eko Akete*.

Mo bẹrẹ f'oji,

Ọjọ pataki lo mbẹ fun awa ọmọ Anabi Adamọ ninu lasigbo aiye wa, ọjọ mẹta jẹ ọjọ ayọ ninu rẹ, ọjọ kan iyoku jẹ ọjọ ibanujẹ.

Ọjọ mẹta ti a ni o jẹ ọjọ ayọ ni Ọjọ—Ibi, ọjọ igbeyawo ati ọjọ ikomọjade, ọjo kan iyoku ni ọjọ ti Asarayilu ba wọ 'le, ninu ọjọ mẹta ti a ni o jẹ ọjọ ayọ, eyiti o jẹ ọjọ ti o wuwo julọ ni ọjọ ti a bi ni gan ti a fi ori ẹni ṣọlẹ si aiye ti a si mọ ibi ẹni ti a lọ ri i mọlẹ, ọjọ yi li a npe ni Ọjọ—ibi tabi (Birthday) ni ede awọn Oyinbo. Ohun pataki lo jẹ fun wa lati ma ya Ọjọ—ibi wa si papa fun ẹniti o ba mọ riri rẹ.

O mbẹ ninu ọpọlọpọ enia ti nwọn nya Ọjọ—ibi wọn si, ti nwọn si ṣe kokari rẹ ni gbogbo igba ti nwọn si nṣe inawo ribiribi si i pẹlu, bẹ lo si mbẹ fun awọn ẹlomiran pẹlu ti nwọn bikita lati wa Ọjọ—ibi wọn mọ debi ti nwọn o fi sọ wipe awọn le ma fi ọjọ bẹ si nanti, ti a tilẹ wo titi ki a sọ wipe ki ẹlomiran sọ ọjọ ti o daiye, o di ki o ma wo kabikabi, o di ki o ma wo oke, bi bẹkọ o di ohun ti yio ṣẹṣẹ ma so wipe afi ti on ba de ile ki on to le mọ Ọjọ—ibi on, o ṣe! ẹlomiran ya butulu.

Awọn Oyinbo mọ riri Ọjọ—ibi daradara ju awọn Enia Dudu lọ, ni ilọpo mẹwa, ki a fi ibi eyi wo; ọdun ti awọn Kiriyo ma nṣe lọdọdun ninu oṣu December, ti nwọn npe ni Keresimesi, Ọjọ—ibi Jesu tabi Anabi Issa ti nwọn nṣe, nwọn si nṣe ọdun nla New year ni arin ọjọ kẹjọ rẹ fun ibẹrẹsi ka oṣu tuntun fun eyiti o ka 'sẹ nilẹ o daju wipe owo ti Kiriyo omiran nna si ọdun Keresimesi ti a wi yi ni aseko rẹ ko ni 'ye, Ọjọ—ibi Jesu ni Kiriyo si mu ni pataki julọ ninu gbogbo-ọdun ti nwọn nṣe larin ẹsin wọn, ọdun ti ko ba tun jẹ pataki fun wọn ni Easter Ọjọ Ajinde Jesu Kristi ti nwọn sọ wipe nwọn kan an mọ Agbelebu ni Ọjọ Jimọ, O si ji dide ni owurọ ọjọ ọsẹ, gẹgẹbi Maria Magalene ti wà Jesu lọ si iboji ti o si ba awọn alaṣọ funfuu meji lori okuta iboji Jesu ti o si mbi wọn lere bi Jesu ti ji dide bi koi ti ji dide, ọrọ pọ ninu iyẹn nitori a ko nwa lati ṣe iwasu Bibeli nihin loni, sugbọn ọrọ ti o ba lọ nipa rẹ tabi nipa Alukurani a'le yan lọpa fi kun ọrọ sọ ohun ti a fẹ ki a mo ni wipe awọn Kiriyo ko ni ọdun kan pataki kan ti nwọn nṣe ti o ju ọdun Keresimesi (Christmas) tabi Ọjọ—ibi Anabi Issa ti nwọn npe ni Jesu amọ ni iyoku jẹ, bi awọn Kiriyo ti nṣe Ọjọ—ibi Jesu ni ọdun pataki, bẹni awọn Musulumi papa nṣe Ọjọ—ibi Anabi Mọmọdu eyiti nwọn ni "Rabiu Awal" ni ede tiwọn, ṣugbọn ko si kokari tobẹ ninu rẹ bi ọdun gan ti nwọn npe ni ọdun Kekere "Eidil Fitri ati ọdun, ọdun-nla "Eidil Azuah" ọdun eyiti awọn arawọn nlọ gun Oke Arafat ni ilu Sarubawa ti nwọn npe ni *Mecca* ti awọn obinrin gbẹgbẹlẹ ihahin bi awọn Salamọtu tabi Ajikẹ yi ma ṣe kẹkẹlukẹ ẹran ileya ti gbogbo rẹ yio si ma ṣe ṣin in-in ni iṣasun bi igbati awọn Kiriyo miran papa nfi wereke sọrọ ninu tumati ati ata nla.

Iba ṣe wipe gẹgẹbi awọn Kiriyo ti mu Ọjọ—ibi Anabi Issa ni okukondu bẹni awọn Musulumi papa si mu ti Ọjọ—ibi Anabi Mọmọdu, I ba dara pupọ, eyi ko di ọdun miran lọwọ fun wọn lati ma ṣe gẹgẹbi nwọn ti nṣe lati ẹhin wa, a si ro wipe o ṣe nye awọn Musulumi papa gẹgẹbi ohun ti a nwi yi, nitoripe nwọn nmura si Ọjọ—ibi Anabi Mọmọdu, ni ihin yi gẹgẹbi ti igba kan ri lọ.

Ni ọdun to kọja ati ni ọdun yi awọn Ijọ Ahmadiya ati awọn Asarud-din Kekere fi iwe si ode lati fi ṣe aisun Ọjọ ti nwọn bi Anabi wọn Mọmọdu, eyi si mu ki olukuluku ṣe Mọṣalaṣi wọn lọṣọ lati fihan wipe Ọja pataki ni Ọjọ na jẹ fun wọn.

Ninu wasu kan ti a gbọ wipe nwon ṣe ni arin ọsẹ to kọja nwọn sọ wipe Anabi Mọmọdu ni Ojiṣẹ tabi (Prophet) igbẹhin ti Oluwa yio gbe dide, O si ti gbe e dide, ki yio si tun gbe Ojiṣẹ kan dide mẹ lẹhin Anabi Mọmọdu, nwọn si nfẹ ki awọn Onigbagbọ miran mọ wipe Anabi Issa ti sọ asọtẹlẹ Anabi Mọmọdu—igbagbọ ti awa ni wipe Anabi Issa Ojiṣẹ Ọlọrun ni Anabi Mọmọdu Ojiṣẹ

Ọlọrun ni bakanna, ṣugbọn iyapa tabi ede aiyede to mbẹ ninu rẹ larin awọn Kiriyo ati awọn Musulumi ni wipe awọn Kiriyo ni Anabi Issa nwón kan an mó agbelebu o ji ni Ọjọ kẹta rẹ, Ọjọ ti nwọn nṣe isin (*Sunday*) O si gun Oke re ọrun, O si joko lọwọ Ọtun Baba Olodumare, mbẹ ni yio ma ṣe idajọ ayè on oku; ati pelu Jesu ku iku Oro fun itori ẹṣẹ awọn ni; awọn Musulumi si nsọ ẹwẹ wipe Jesu ko ku nitori ẹṣẹ ẹnikẹni, ati pẹlu nitotó, o ku ṣugbọn ki iṣe ori agbelebu gan ti awọn Yẹwudi tabi awọn Ọrẹ Gudasi ti pese silẹ ti Anabi Issa ku si, igbagbọ ti won ni wipe oku bi enia ti ni lati ku, nwọn si sin oku rẹ si iboji kan ni ilu kan ni iwaju Jerusalem bẹni ko si lọ joko si oke ọrun lati ba Ọlọrun ṣe sawawu pọ tabi ibikeji Ọlọrun gẹgẹbi awọn Ọlọrunmila ti npe kini kan ni ibikeji lẹnu wọn lọhun.

Ti o ba jẹ wipe gegẹbi awọn Musulumi ti gba Anabi Issa ni Ojiṣẹ Ọlọrun ti nwọn si gba gbogbo ọrọ rẹ ti o mbẹ ninu Alukurani ni awọn Kiriyo si gba Anabi Mọmọdu gbọ wipe Ojiṣẹ Ọlọrun ni ati pẹlu ki yio si tun si Ojiṣẹ Omiran mọ ti a o gbe dide, tabi ti a o fi Tira tabi iwe omiran le e lọwọ mọ, ọrọ wọn iba fuyẹ diẹ ani larin Kiriyo ati Imale, ṣugbọn nipa ai si eyi lo nmu ara won ko ọrọ ara wọn, lo si nmu kiriyo omiran korira Imale miran nigbati nwọn ba pade ara wọn ni ibi anfani pataki kan.

Ṣugbọn awọn ti o jẹ ọlọgbọn ninu Imale ati Kiriyo ti mọ wipe ka ga ka go ede ni o ye de, ọkan wa ni alfa wa.

Ki o maṣe jẹ iyalẹnu fun wa nigbati a ba sọ nisisiyi pe geregan ni a ma ba Aborịṣa miran ninu Alijanna ki a ma ṣẹṣẹ so ti Kiriyo mọ lọjọ Alikiyoma, ti a o si tun ba Musulumi miran ẹwẹ ninu Ọgba ina ti ina yio si ma jo o bula-bula bi katiaku, ti yio si ma kegbẹ ibanujẹ wipe nwọn ṣe wasi fun on titi eṣu lo ntan on lọ nfi owu elepo pupa di on lọti ni ko jẹki on gbọ 'ran mọ, ki olukuluku lọ toju iwa rẹ, bi aiye ba nda fun ni kole to ti Orun, nitoripe ti ọrun lo julo, ki a ma si ṣe ro larin iṣẹju kan, pe ati Kiriyo ati Imale ati Aborịṣa a ki yio jihin iṣẹ ti olukuluku wa ṣe lọjọ Igbende, dajudaju a o jihin rẹ, iṣebọsi ni isọfun bi a ti wa aiye gan bẹ li a o lọ, igba ti a wa aiye tilẹ san daradara ju igba ti a nlọ lọ.

Nisisiyi, ẹnikan l'yun, a o ma gba adura ki o le bi tibi tire ki Ọlọrun maṣe jẹki oluwarẹ kan agbako awọn ọmọ Araiye lọjọ ti Sati ba jaja da oluwarẹ silẹ, ti a gbọ ohun iya ti a si gbọ ohun ọmọ, igbe barika li a o ma ke lọtun ati l si, lẹsẹkẹsẹ a o ti gbe ọmọ na a o ti ṣe ọjọjọ ararẹ, a o si ma du ọmọ na ni adugba, ki a to gbe pọn, njẹ ti igba ti a nlọ ha ri bẹ? Agbẹdọ ko ri bẹ, bi o ti wu ki oku na le dun ni to, ere iwe li a o ma sa, ki o le tete tẹ wa lọwọ, ki a le gbe oku na yẹra kuro ni ile lọ sin, ki õrun rẹ ma ba gba ile kan, bi o ti wu ki oluwarẹ le to, kutakuta rẹ pin lọjọ na ni iyẹn, eyi to wasu kan fun wa.

Nipa Ọjọ—ibi ti a nsọrọ le lori lo mu wa ya lọ fi ẹnu kan ọrọ Ọlọrun, ohun pataki lo jẹ fun olukuluku wa, ti ki iṣe ọjọ ti o yẹ lati fi ṣire arara, lọdọdun ni awọn ẹlomiran nṣe inawo Ọjọ—ibi wọn, ẹlomiran nṣe lọdun marun-marun, ẹlomiran ọdun mẹwa bẹ bẹ lọ, bi olukaluku ba ti fẹ tirẹ si ni Ọrọ Ọlọrun ni ko mu ija wa, ẹlomiran kosi mọ eyi yi si ohun pataki, on ti wa aiye na, nwọn si ti ko on jade ni ọjọ keje ti aṣa awọn Kiriya tabi ti Yoruba ati ni ọjọ kẹjọ ti awọn Musulumi gẹgẹbi aṣa tiwọn papa, njẹ nigbati nwọn bi Anabi Mọmọdu ni aya ọjọ *Monday* ijẹta ọjọ Suna rẹ ni lati tun ku ọla nitorina a ba gbogbo awọn Musulumi yọ patapata nwọn ku ewu o, ki Ọlọrun ma ṣe eyi ni aṣemọ mọ—*fatiha*.

## ẸJỌ MAKỌLI ATI KỌLKRIKI.

Ni ọjọ *Monday*, ọjọ kẹtadinlọgbọn oṣu *August* ni Onidajọ H. A. Young, K.C., ṣe idajọ rẹ fun Ọgbẹni Macaulay, C.E., ati Dokita Caulcrick nipa ẹjọ ọrọ ọtẹ Ẹtu Ibọn ti o mbẹ ninu iwe irohin *Daily News* ti ọjọ 29 June 1928, wipe ki Dokita Caulcrick san adọta pọnun tabi ẹwọn oṣu mẹta, ki Ọgbẹni Macaulay lọ si ẹwọn oṣu mẹfa.

Emi ni ti nyin nitotọ,

KEKERE-AWO.

---

## THY WILL BE DONE.

It is with deepest regret we chronicle the death of Mrs. Comfort Duroorikẹ Beckley, wife of Mr. Albert Ọlasọde Beckley, which sad occurrence took place at Taiwo Street, Ikorodu Villa, on Friday the 24th August, 1928, at about 5.30., p.m.

The funeral service took place the following afternoon at St. Paul's Church, Breadfruit at 3.50 p.m., before a large concourse of people. The Venerable T. A. J. Ogunbiyi, LTH., Archdeacon of Lagos, and Rev. C. A. Sowunmi, M.A., officiated. And from thence to Ikoyi Cemetry for interment.

The late Mrs. Comfort Beckley was a good christian, and regular in Church attendance; she was a member of St. Paul's Church, Breadfruit Ifẹ'oju Society.

The deceased married in November 1908, and left two children to mourn her loss at the age of 41.

To her husband Mr. A. O. Beckley, Mrs. J. Bagan Benjamin her cousin and the rest family of the deceased we tender our heartfelt sympathy.

May she rest in peace.

OLUSAKIN.

*Gẹgẹ bi mo ti nba irohin mi bọ nipa titumọ irohin Ijọba (Gazelle) eyiti ko ti pari ninu irohin na ni wọnyi :—*

Ati pe awa papa ṣe akiyesi nipa fifi aye silẹ fun dida Igbimọ aṣelu nipa yiyi ofin lati fi omiran si ni, nipa ṣiṣe ofin lati ọwọ Gomina ati Igbimọ aṣofin na.

Njẹ, nitorina, Awa ṣe, nipa gbogbo aṣẹ fifi kun yi nipa ọwọ ati otitẹ we pataki, lati ọjọ ikede, ti Gomina wa yio tẹ sode tabi adele Gomina ti ijọba gbogbo ilu ninu iwe irohin ijọba tẹ lai si Ikorira tabi ti o tẹ le ofin ti ẹṣẹ kẹrin ati karun ti inu aṣẹ wa ti ọjọ kesan oṣu *December*, 1922 ati wipe awa si lanọ asi fi we ara wọn asi kede ifẹ wa ati itẹlọrun wa, lati ọjọ ikede ti aṣẹ wa ti ọjọ kẹsan oṣu *December*, 1922. ni lati yi gẹgẹ bi ẹni pe afi di ẹsẹ ninu ilana dipo ẹsẹ kẹrin ati Ikẹdogun ti nu ilana na.

iv. Ẹgbẹ Igbimọ Aṣelu ti ilu ni lati jẹ awọn ẹniti ao ka wọn yi iyẹn ni pe :—Oṣiṣẹ ti o nṣe iṣẹ akonṣe pataki fun Ijọba *Chief Secretary to the Government* awọn ọtun Gomina ti gbogbo *Nigeria Lient Governor* Olotu ofin *Attorney General* Olotu awọn Ṣọja, Olotu awọn Dokita, Akapo owo ijọba ti gbogbo *Nigeria*, ẹniti a le pe bi ẹnipe ki nṣe onişẹ ọba bi Ẹgbẹ ati ẹnikẹni ti a ba yan nipa aṣẹ tabi iwe ipa ni asiko ka siko nipa aṣẹ ọwọ wa tabi ti Gomina, ninu aṣẹ ti a wi yi lati ọdọ wa, lati ọwọ awọn akọwe wa pataki ti ofin, le ni asiko ka siko nipa aṣẹ ti o ni otitẹ ilu ninu, tabi ti a le fi aye yi yan ya lati ọwọ Gomina ni ọna ti a yan silẹ yi.

Nigbakigba lori ohun pataki ti Gomina ba fẹ lati gba imọran lọwọ ẹnikẹni ni ilu *Nigeria* ti o ole fi ọwọ kan nkan ti wa ninu rẹ, ole, nipa ilanọ ti owa ninu otitẹ gbogbo ilu, le pe ipe fun ohun pataki fun ẹnikẹni lati jẹ aṣẹṣẹ yan ni ẹgbẹ aṣelu fun igba yan nikan.

Eyiyi ni afi kun aṣẹ si

Gomina ati alaşẹ gbogbo ilu *Nigeria*.

xv. Nipa dida ofin tabi şiṣe ofin Gomina ati gbagbo Ẹgbẹ Igbimọ aṣofin ni lati ṣe akiyesi gẹgẹ bi agbara wọn ba ti wọ nipa nkan wọnyi :—

1. Gbogbo ofin ko fin ni a ni lati fi oriki wọn mọ wọn, asi ni lati pin wọn si ọna totọ ati ẹsẹṣ asi ni lati fun wọn ni eto kọkan, ati ni ori kankan ani lati fi aye diẹ siwaju rẹ eyiti ao tẹ niba ṣoki ohunkohun to ba wa ninu ori kankan. Awọn ofin ọdun kọkan ati lati di wọn pọ pẹlu eyikeyi ti a ba ṣe pẹlu rẹ, eyiti a ba ninu ẹsẹ xxiv ati xxiva ti ilu Nigeria (Igbimọ Aṣofin) aṣẹ ni Igbimọ, 1922, ati awọn ofin wọnyi fun ti ilẹ Hausa (Northern Province) ti gbogbogbo ẹku Nigeria ati aṣẹ ni Igbimọ ti cdun 1922 ani lati fun wọn ni etu kankan ati eyi ti abẹrẹ ninu ọdun na ni eto kini. Aya fi ninu iwe ọwọ (Bills) eyiti ao fi ranşẹ fun ọwọ wa ati itẹlọrun wa, gbogbo ofin ti Igbimọ Aṣofin fi ọwọ si ninu ọdun kọdun kan le, bi Gomina fi si fifi si ti ọdun na, ati pe ani lati fi ọjọ si lati ijọ ti Gomina fi aṣẹ si, şigbọn Gomina ni lati fi ti, fun ohun ti wa ti aba ni itẹlọrun si nigbana ni ao fi ọjọ si ati eto lati inu odun na lọ ti ti di igba ti ao bẹrẹ si lo.—

2. Nkan ti o ba yatọ si ara wọn, ani lati fun ni aye lati ṣe ofin ti o ba olukuluku won ninu, lai da ọkan sinu ikeji nipa ofin, iyẹn ni ka ma fi ofin kan na lo awọn mejeji ati ohun ti ko nipa tabi ni agbara ti won fi le kan ara wọn; ati pe ẹsẹ kẹsẹ kan ko ni lati wa inu rẹ, tabi ki o ba ofin ti a le pe ni ajeji si eyiti oriki ofin na le mu wa ati pe ko ni si aye kan fun ofin ti ko ni ijoko pataki.

Lati ọwọ wa ni Ile ofin ti Saint James ni oni ijọ kẹtadilogun oşu February 1928 ni ọdun kejidilogun ti ijọba wa.

(*a o ma ba bọ*)

**Emi ni ti nyin nitotọ,**

**Enia ko da bi Allah.**

---

# *Olusakin's Column.*

---

**Not Passing Rich.**

***From the Church of England Newspaper.***

Although the nominal income of the Archbishop of Canterbury is £15,000 the rates and taxes on two "Palaces" combined with the official expenses are so heavy, that very little is left for the personal use of the Archbishop. Dr. and Mrs. Randall Davidson have lived in a most homely fashion, and yet, they are by no means passing rich on £15,000 a year.

---

**A Matrimonial Difficulty.**

Dr. Lang is a bachelor. In this connection a well-known story has been recalled. When

Dr. Lang was at Portsea, where he had sixteen curates, Queen Victoria suggested to him that he might dispense, with two or three curates if he had a wife. His reply was to effect that he could dispose of his curates, but a wife would be another matter?

---

WOMAN BACHELOR OF DIVINITY.

The wife of an Aberystwyth business man, Mrs. Mabel Bickerstaff, has passed the final Bachelor of Divinity examination of London University. She accomplished this in two years, the shortest time possible, studying privately. Mrs. Bickerstaff was already an M. A., of the Welsh University, She is the daughter of late Professor Edwin Williams, B A, of Trefecca, who was well-Known as a preacher and teacher.—*The Church of England Newspaper*, *3/8/28*.

---

PROMOTION.

Mr. E. A. Alade, Senior Pay Clerk, Accounts Department, Nigerian Railway, Ebute Metta, has been promoted to the rank of an Assistant Chief Clerk, as from the 1st April, 1928. Heartiest Congratulation.

---

VICAR MARRIES HIS HOUSEKEEPER.

The marriage of the Rev M. E. Davies. Vicar of St. Mary's Parish Church, Abergavenny, to his housekeeper, Miss, George, tooks place quietly at Sutton, Hereford, yesterday. The ceremony was performed by a brother of the bridegroom, the Rev. Davies, of Ruabon, and only a few intimate friends were present.—*News of the World*, *5/8/28*.

---

MARRIED SIXTY YEARS.

Mr. and Mrs. James Barnett, the joint attendants at the Court House, Northallerton, have just celebrated their diamond wedding. Mr. Barnett is captain of the Northallerton Parist Church bell ringers, and has rung bells for 63 years. He is 79 and his wife 78. Both are active and well.—*News of the World.*

---

THE "ELEKO OF EKO"

A new and interesting claim in connection with the title assumed by Prince Ibikunle has been made in Lagos. It is that he is the "Eleko of Eko," and that the word "Eleko in this instance is not inherited from his predecessor, but is a title formed from the local name of Lagos, according to the ordinary rules of Yoruba grammar. This is interesting, since it is a tacit admission that hitherto "Eleko" has not been the name of a ruler, but has been, as Prince Esugbayi's friends have claimed, nothing but a nickname. On the other hand, the assumption of a title so wide in meaning as "Eleko of Eko" would seem to ascribe to the present holder powers much wider than those of the simple family head set forth in Sir Hugh Clifford's definition of the position of the chief member of the Docemo family. At any rate, as a new title coined after some 60 years, of British occupation, it seems to have no great claim to recognition, even by Lagosians themselves.—

*West Africa, 11/8/28.*

---

THE END OF APALARA BASHUA'S CASE.

The case Rex. versus Mr. Apalara Bashua, a well known Songster, who was charged with murder of his step daughter, Comfort, ended last Thursday, the 23rd August, 1928. Jurors returned verdict of not guilty and the accused Apalara was thereby discharged. Oku ori re.

---

THE DEATH OF MRS. HANNA SAVAGE.

The death occurred on Tuesday night, the 21st August, 1928, at her residence, 18 Martins Steet, Lagos.

The funeral service took place the following afternoon at St. Paul's Church Breadfruit, the 22nd ultimo, at 4 p m., and her remains were removed to Ikoyi Cemetery for interment.

The late Mammy Savage was an exemplary Christian, and died at an advance age little over 100 years.

To Mrs. Caroline Harding, Mr. S. Williamson Savage, Mr. Alfred Large, and other members of the bereaved family, our condolence. R.I.P.

---

OBITUARY.

The death is reported as having taken place on Friday, the 24th August 1928, of Mr. Joakin S. Martins, of 57 Kosoko Street, Lagos, at about 8.20 a.m.,

The funeral service took place the following morning at Jehovah Shallon Church, at 8 a.m., before a large crowd of people. Rev. D. A. Bababunmi officiated. And to Ikoyi Cemetery for Interment.

To Mrs. M. M. Rotimi, Mr. Jonathan Martins and Mrs. S. A. Thomas and to the rest family of the deceased—condolence.

May he rest in peace.

OLUṢAKIN.

## Beware of the season.

Use Dr. Skelton's Influenza and Cold Cure strongly recommended for this Owore Season 2/6d.

## That Wonderful Female Pill!

Wireless Female Pills instils new life in women, recommended for all functional disorders peculiar to women. It regulates the system and prevents barreness 4/- per bottle.

## New Life for Men.

Life Tonic Tablet will revitalise you; this wonderful Tablet costs you 3/- only. Get a bottle.

## Yaro! Yaro! Yaro!

No more pain for children cutting teeth, use 'Yaro' Infant's favourite Preservative. It prevents convulsion &c., &c. 2/3d and 3/3d per bottle.

### Do away with Piles!

Get rid of Piles that loathsome disease by using:—

Effective Pile Remedy 7/6d

Pile Pills 1/6d

Pile Ointment 2/-

### Kaduna Balm.

Every Home requires Kaduna Balm, the family Remedy applicable in 100 different ways. 1/-

### Don't grow old whilst you are still Young.

Dr. De Roos' concentrated Guittae Vitae will bring you back to Health and Beauty. Recommended for general debility, dimness of sight, shaking of the hands and limbs—miraculous curer £2 2s. (largest size)

### We also stock:—

Elixir Hydrastin 10/6d
Elixir Avena with Helonias Compound 10/6d
Sacharine 1/- & 1/6d
Male Tonic 10/6d
Cooling Blood Purifier 7/6d
Vibrona Wine 7/6d

*Obtainable at:—*

# IYIN OLUWA MEDICINE STORES

*Head Office:*—88, Broad Street, Lagos,
*Branches:*—6, Martins Street,
41, Alli Street, Faji Market,
10? Griffith Street, Ebute-Metta

## White's Golden Male Tonic

DOUBLE STRENGTH).

Whenver a woman has not been in the family way for a long time, the fault is usually set down to some disease or other in her generative organs.

Now while it is true that many women suffer from disease, yet many times the fault lies with the man, owing to weakness or some other disease of the male organs of generation. White's Golden Male Tonic (Double-Strength) is calculated to give full vigour to the man, and to remove all diseases which prevent breeding. Every sensible man ought to use two bottles every month, to cure or prevent weakness of the generative organs.

Made and sold only by VICTOR WHITE, Esq.,
*The Reliable Dispensary, 41, Offin Road, Lagos.*
*N.B.*—NOT OBTAINABLE ELSEWHERE.
"Shake the Bottle."

AREMỌ FUN ỌKUNRIN.

Nigbati obinrin ko ba tete loyun, a ma nro pe ara obinrin na nikan ni arun wa. Ṣugbọn nigba pupọ ni o nję pe ara ọkunrin ni arun wa. Egbogi yi dara pupọ fun Arę, Ẹda ati gbogbo arun ti ki jẹ ki ọkunrin ṣe abiamọ.

*N.B.*—O yẹ ki gbogbo ọkunrin ma lo igo meji-meji loṣoṣu—Iṣẹ ti egbogi na nṣe ni ara ko ṣe royin.

Price TEN SHILLINGS (10s) per bottle.

*Postage 2/6 extra.*

## White's Golden Female Tonic

A splended Remedy for Female diseases such as:—Barrenness, Weakness, Painfull and Irregular, Menstruation Leucorrhœa (Whites) Cramps, Ovarian, Neuralgia, Inflammation of the Ovaries. A Tendency to Miscarriage etc, etc.

Made and sold only by VICTOR WHITE Esq.
41, Offin Road, Lagos.
*N.B:—Not obtainable elsewhere.*

GBOGBONIṢE FUN OBINRIN.

Egbogi yi dara pupọ fun Aboyun, Iju, Ẹda, Aran, Oyun ti o ba fẹ bajẹ, ati oriṣiriṣi arun mi ti ki jẹ ki obinrin bimọ.

PRICE 10/- PER BOTTLE.
Postage 2/6 extra.

WHITE'S

## WONDERFUL BRAIN TONIC

This medicine stimulates and rebuilds the brain in such a way, that the regular user is able to do many times the usual amount of Brainwork that he used to do, before using it. To Brainworkers and those who have examinations to pass, it is a boon.

Made and sold only by SAMUEL VICTOR WHITE, Esq.
41, OFFIN ROAD, LAGOS.

Large size 5/- per bottle. Packing and Postage 2/6 extra.
Small size, 2/6 per bottle. Packing and Postage 1/6 extra.
N.B.—*Scholars should not be without it.*

EGBOGI ISỌYE.

Egbogi yi dara pupọ fun awọn ọmọ-ile-iwe awọn ti o nfi iwe ṣiṣẹ ati gbogbo awọn ti o ba ni lati lọ fun idanwo.

*Iba ṣe ọmọde tabi agbalagba.*

## White's Golden Blood Restorer

*(A Native preparation for Women.)*

This medicine is an excellent remedy or Insufficiency or Loss of the monthly courses, Tumour in the Womb, False Pregnancy, Catarrh of the Womb, Various Runnings or Morbid Discharges from the Womb (especially those that are long-standing).

Sick Headaches, Dizziness, etc., etc.

Made and sold only by
VICTOR WHITE, ESQ, *Chemist,*
The Reliable Dispensary, 41, Offin Road, Lagos
"SHAKE THE BOTTLE".
Price TEN SHILLINGS (10/-) per bottle.
*Packing and Postage 2/6 extra, to any part of Nigeria.*

EGBOGI ILANA ẸJẸ FUN OBINRIN.

Egbogi yi dara pupọ fun obinrin ti ko ba ri nkan oṣu rẹ mọ (lalai to aseko), nkan obinrin ti ko ba pọ to. Aṣẹ Ewurẹ pipọju, Ẹda ti o ba gbo, Ẹyo, Oyun-koyun. Oyun ti ko ba dagba, Oyi, Ẹsanri ni akoko hela, Aran ati Iju.

## HORSFIELD'S

The well known suppliers of all classes of goods under the registered Trade "ZODIAC" Mark.

Call and see our Agent and give your orders to :—

MR. MOSES O. COKER,
Port Novo Market Street, Lagos.

who has samples every mail of all the latest styles of fancy and other goods, including our REGISTERED Palm Tree and Feather Embroideries.

We supply everything.

J. J. HORSFIELD & CO.,
( Manchester ) Limited,
65, George Street,
Manchester.

---

### GOOD MARKET.

Gonorrhea Specific, Moloke Mone, A. & D. Bula Matadi for health-restoring purposes: these Medicines are on sale at Mr. H. Campos's First Class Shop, 37, Odunlami Street, Lagos. The Specific acts like Magic : has cured many obstinate cases, and *will cure yours just the same*, if any.

Cheap Goods! Superior Quality!! Quick Fortune!!!

---

*Cable Address* :—" WHITE LAGOS".

MR J. T. AKIREMI WHITE
P.O. Box 82
20, Balogun & Breadfruit Streets
or
41, Offin Road, Lagos.

### Indents House.

Import of General Lines
Export of Produce Commission Agencies undetaken.

Correspondence invited.

With over 22 years' experience in this line of business.

Mr. White's well-known connexion with reliable Firms in Europe is a matter of common knowledge to his clients.

A Trial is Solicited.

---

When replying advertisers please mention *Eko Akete*

---

## TO LET.

**One Splendid Pleasure Car**

No. L2754.

***Always at everybody's service at Tinubu Square.***

For Terms, Apply to —

A. B. Williams,
14, Bishop Street, Lagos.

# ILE OWO OYINBO

# JOHN RADCLIFFE

## Ni No. 63, Ehingbeti, Eko.

———:o:———

Ile-owo ti o wuyi fun ọja meremere bi Ṣẹda, aṣọ Yọ[...] ati aṣọ ti a fi ẹlẹya Oyinbo gbaleti.

Ẹ wa bẹ orişirişi ọja wa wo ni Ile-owo wa titun to k[...] si Ile Niger ni No. 63, Ẹhingbẹti.

Aṣọ lorişirişi ni aṣetejọ: aṣọ Ṣẹda ati Siliki mbẹ bi [...] awọn wọnyi jẹ eyiti awọn onibara ṣa ti nwọn si ti sami si [...] ra wọn. Aṣọ lami-titi ti a npe ni Ṣantọnu nkọlu 'ra wọn.

Agbalẹtu ni gbogbo ọja wa fun didara wọn.

Pọ ọ si ni owo wọn.


Printed at "Tika-Tore" Printing Press, 20, Market Street, Lagos, and Published [by] Adeoye Deniga at 24, Williams Street, Lagos, Writer and Lecturer.